# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

## OSÙ KẸTA, ỌDÚN 2022

### Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́

## OṢÙ KẸTA 2022 – DÍDÒJÚKỌ ÀWỌN ẸMÍ ÒKÙNKÙN ÀJÀKÁLẸ̀-ÀRÙN TÓKÁRÍ AYÉ (1)

7:00 am – 7:05 am Àdúrà ìbẹ̀rẹ̀
7:05 am – 7:20am Orin Ìyìn àti Ijọ́sìn
7:20 am – 7:35 am Ijẹ́rì
7:35 am – 7:45 am Wákàtí Ìṣìpẹ̀ Àdágbà
7:45 a m – 8:45 am Iṣẹ́ Ìránṣẹ́
8:45 am - 9:00 am Ọrẹ àti Ìparí ìpàdé

1. **Jí, sọ agbára Rẹ d'ọ̀tun**

Gbé hàmọ́ra ogun rẹ wọ̀;
A o ṣẹ́gun gbogbo ọ̀tá
Krístì yó sì jọba.
Krístì y'ó jọba
Krístì y'ó jọba
Irètí wa n'nú Rẹ kò yẹ̀;
Krístì y'ó jọba
Krístì y'ó jọba
Krístì y'ó jọba
Irètí wa n'nú Rẹ kò yẹ̀;
Krístì y'ó jọba

2. Ó ti pẹ́ t'áwọn ọmọ Rẹ

Tí nṣẹ 'yapa lórí ẹ̀kọ́;
Wọ́n gbàgbé pé l'órí ṣọ̀kan
Ni Òn lo ayé Rẹ
Krístì y'ó jọba
Krístì y'ó jọba
Irètí wa n'nú Rẹ kò yẹ̀;
Krístì y'ó jọba

Krístì y’ó jọba
Krístì y’ó jọba
Irètí wa n’nú Rẹ kò yẹ̀;
Krístì y’ó jọba

3. Ẹ papọ̀ ní agbára Rẹ
Ayè yin yó sì jẹ èrè
Láìpẹ́ ẹ ò ní ìṣẹ́gun
‘Torí Kríst’y’o jọba
Krístì y’ó jọba
Krístì y’ó jọba
Irètí wa n’nú Rẹ kò yẹ̀;
Krístì y’ó jọba
Krístì y’ó jọba
Krístì y’ó jọba
Irètí wa n’nú Rẹ kò yẹ̀;
Krístì y’ó jọba

4. Ó yẹ ka ṣìṣẹ́ f’Ólúwa,
Iṣẹ́ wa kò jẹ́ asán;
A kò gbọdọ̀ padà s’ẹ́yìn,
‘Torí Krístì y’ó jọba
Krístì y’ó jọba
Krístì y’ó jọba
Irètí wa n’nú Rẹ kò yẹ̀;
Krístì y’ó jọba
Krístì y’ó jọba
Krístì y’ó jọba
Irètí wa n’nú Rẹ kò yẹ̀;
Krístì y’ó jọba

## ỌRỌ̀ AGBÁRA

1. Ọlọ́run, nínú ètò Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́ osù yìí, Dìde, fi orísun àwọn iṣòro olóríkunkun nínú ayé mi hàn mí, kí O sì fi ọ̀nà àbáyọ hàn mí, ní orúkọ Jésù.
2. Gbogbo agbára tó n pe awòrán mi lórí pẹpẹ ibi, àrá iná Ọlọ́run yóò pa yín run lónìí, ní orúkọ Jésù.
3. Agbárákágbara tí kò fẹ́ kí n dá anfànì mi mọ̀ nígbà yòówù tí ó bá dé, mo gbé ọ sin lónìí, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo gbólóhùn tó wí pé kò sí ẹni tí yóò ràn mí lọ́wọ́ àfi igbàtí mo bá darúgbó, mo fagilé àwọn ọ̀rọ̀ rẹ lónìí, nipa agbára tówà nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù.
5. Àwọn agbára òkùnkùn tọ́ wí pé àwọn yóò bámi jà títí dé ibojì, irọ́ lo pa, ìwọ yóò kú lónìí, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo agbára òkùnkùn, tó wí pé ogun mi kì yóò dópin, opùrọ́ ni ọ́, mo gbé ọ sin síbí yìí lónìí, ní orúkọ Jésù.
7. Ìkórajọpọ̀ àwọn ẹ̀mí òkùnkùn nínú ìdílé mi, tí wọ́n wí pé àfi tí àwọn bákú ni moma tó rí àwọn alàjá mi, Olúwa bá ọ wí lónìí, túká sí idahoro, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ

**Ìjẹ́wọ́: Orin Dáfídì 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Gbogbo odi ààlè ìkọ̀kọ̀, tó dèmí mọ́lẹ̀, fọ́, kí o sì túká sí wẹ́wẹ́, ní orúkọ Jésù.

4. Gbogbo ọ̀rọ̀ tí wọ́n sọ lábẹ́ ìfòróróyàn òkùnkùn, tó lódì sí ayànmọ́ mi, gbaná, fọ́, kí o sì túká, ní orúkọ Jésù.
5. Ọ̀rọ̀ ibi yòówù tí wọ́n lo láti sọ ògo mi di ohun tíkò leè ṣe, ta padà, ní orúkọ Jésù.
6. Àwọn iṣòro tó fẹ́ darí ayé mi, mo pàṣẹ kí ẹ poòrá, ní orúkọ Jésù.
7. Ọlọ́run, dìde, ti ìfẹ́ àti ìpinnu Rẹ lẹ́yìn nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.

## <u>ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ</u>

**Isàíàh 33:2** Olúwa, ṣànú fún wa; àwa ti dúró dè ọ́: ìwọ ma ṣe apá wọn lí oròwúrọ̀ àní ìgbàlà wa nígbà ìpọ́njú.

**Isaiah 40:1** Ẹ tu ènìyàn mi nínú, ẹ tù wọ́n nínú, ni Ọlọ́run nyin wí.

**Isàíàh 53:5** Ṣùgbọ́n á ṣá á li ọgbẹ́ nítorí ìrékọjá wa, a pá á li ara nítorí àìṣedédé wa; ìná àlàfíá wa wà lára rẹ̀, àti nípa ìnà rẹ̀ li a fi mú wa lára dá.

**Lúkù 4:18** Ẹ̀mí Olúwa mbẹ lára mi, nítorítí ó fi àmì oròró yán mi láti wásù ihìnrere fún àwọn otòṣì; ó ti ràn mi wá láti ṣe iwòsàn àwọn ọkàn oníròbìnújẹ́, láti wásù ìdàsílẹ̀ fún àwọn ìgbèkùn, ìtúnríran fún àwọn afọ́jú, àti láti jọ̀wọ́ àwọn tí a pa lára lọ́wọ́.

**Máttéù 9:35** Jésù sì rìn sí gbogbo ìlú-nlá àti ìletò, ó nkọ́ni nínú sínágógù wọn, ó sì nwásù ihìnrere ijọ̀ba, ó sì nṣe ìwòsàn àrùn àti gbogbo aìsàn lí ara àwọn ènìyàn.

**Márkù 5:34** Ó sì wí fún u pé, Ọmọbìnrin, igbàgbọ́ rẹ mú ọ láradá; ma lọ lí alàfíà, kí ìwọ kí ó sì sàn nínú arùn rẹ.

**Máttéù 14:14** Jésù jáde lọ, ó rí ọpọ̀lọpọ̀ ènìyàn, inú rẹ sì yọ̀ sí wọn, ó sì ṣe dídá àrùn ara wọn.

**Jòhánnù 14:27** Alàfíà ni mo fi sílẹ̀ fún nyin, alàfíà mi ni mo fifún nyin: kí íṣe gẹ́gẹ́ bí ayé íti fi fúnni lí èmi fifún nyin. Ẹ máṣe jẹ́ kí ọkàn nyín dàrú; ẹ má sì jẹ́ kí ó wárìrí.

**2 Kọ́ríntì 2:14** Ṣùgbọ́n ọpẹ́ ni fún Ọlọ́run, ẹnití nyọ ayọ̀ ìṣẹ́gun lórí wa nígbàgbogbo nínú Krístì, tí ó sì nfi orun ìmọ̀ rẹ hàn nípa wa níbigbogbo.

**1 Kọ́ríntì 15:55** Ikú, oró rẹ dà? Isà òkú, ìṣẹ́gun rẹ dà?

**Jósúà 10:8** Olúwa sì wí fún Jósúà pé, Má ṣe bẹ̀rù wọn: nítorítí mo ti fi wọn lé ọ lọ́wọ́; kí yóò sí ọkùnrin kán nínú wọn tí yóò lè dúró níwájú rẹ.

**Ìfihàn 12:11** Nwọ́n sì ṣẹ́gun rẹ nítorí ẹ̀jẹ̀ Ọ̀dọ̀-Àgúntàn na, àti nítorí ọ̀rọ̀ ẹ̀rí wọn, nwọ́n kò sì fẹ́rán ẹ̀mí wọn àní títí dé ikú.

**Hébérù 4:12** Nítorí ọ̀rọ̀ Ọlọ́run yè, ó sì lí agbára, ó sì mú ju idàk'ídà olójú méjì lọ, ó sì ngúnni àní títí dé pípín ọkàn àti ẹ̀mí níyà, àti oríkè àti ọ̀rá inú egungun, òn sì ni olùmọ̀ èrò inú àti ète ọkàn.

**Fílíppì 4:13** Èmi lè ṣe ohun gbogbo nínú Krístì ẹnití nfi agbára fún mi.